# IROHIN IMOLE

IMOLE *ORE AIYE TENI* GBOGBO LAWA

No 1,584 MONDAY DECEMBER 13, 1965 (2D)


## Awon Musulumi Fẹ Gbadura

QWQ.— Gẹgẹbi iwe kan ti o de ile iṣẹ wa ni ọjọ Eti-tiṣe ọjọ kẹwa oṣu yi pe, gbogbo awọn aṣiwaju Musulumi ti kesi awọn enia ti o wa ni Qwọ paapa ile Yoruba ki nwọn kun fun adura gidigidi pe alafia ati ifọkanbale Ia le pada si Ipinlẹ Iwọ Orun, iwe na tun sọ siwaju si pe awọn Onigbagbọ na gbọdọ gbadura fun alafia ilẹ Yoruba.

Ninu ọrọ ti Lemọmu agba ilu Qwọ sọ ni o ti ṣe alaye pe, gẹgẹbi ẹlẹsin Qlọrun ti gbagbọ pe, bi ọrọ kan ba le koko bi oju ẹja, adura nikan ni o le jẹki o de bi Ọgẹdẹ ati paapa awọn aṣiwaju Onigbagbọ ti a mọ ni Jesu p lu Osimu sulumi ti a mọ ni Muhamendu, adura ni nwọn fi ṣẹgun gbogbo iṣoro nwọn.

Alhaji Balogun ti o jẹ olori awọn Lemọmu fun Qwọ tun sọ pe, awọn ti nwọn nfi ẹsẹ tu igboro kati nwọn ni awọn yio pari ija to wa larin awọn ẹgbẹ oṣelu nibẹ. O ni yio sọrọ fun wọn bi nwọn ba le ṣe iṣẹ na yọri.

O wa tun rọ awọn Onigbagbọ pe ọrọ na kọse ti awọn Imole nikan o tun kan awọn na pẹlu, o ni ẹniti o ba nifẹ Yoruba lọkan gbọdọ maa da gba adura fun ararẹ ki alafia ba le tete pada si Ipinlẹ Iwọ Orun.

Bẹna tun ni iwe ti a ri gba lati ọwọ alaga ẹgbẹ Qmọ Ekiti ti o nse atipo ni Ondo Ọgbẹni J. A. Aluko, ni on ti kesi Qlọla Alhaji Balewa pe, ki o tete fa awọn Qlọpa Hausa ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun leti lori iwa tani yio m mi ti awọn Hausa nhu si awọn enia na.

WO OJU EWE KẸFA

### Rogbodiyan Bẹsilẹ Ni Owode

# ỌLỌPA MẸFA SỌNU !

## ỌMỌ ẸGBẸ OṢELU KAN KU

IRO-OWODE.— Qrọ di bi o lọ ki o yago kuro lọna fun mi, gbogbo enia si bẹrẹsi sare Qlomọgbomọpọn nigbati awọn Qlọpa de si inu ilu Iro, ilu kan ti ko jinna pupọ si Owode ni ti Abẹokuta ti gbogbo awọn enia inu ilu na si nsare wọ inu ile wọn lọ bi nwọn ti ri awọn Qlọpa ninu mọto nla meji ti nwọn nsọ kale pẹlu ibọn ni ọwọ wọn ni deede agogo mẹfa irọlẹ ana ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi.

ye siwaju pe Obinrin mẹta wa n'nu awọn enia ti ọlọpa mu na.

Wo Oju Ewe Kẹfa

Irohin awọn Qlọpa Abẹokuta fi ye wa pe, ni irọlẹ ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni rogbodiyan kan bẹ silẹ ninu ilu na larin awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ati ọmọ ẹgbẹ UPGA ti awọn majeji si bẹrẹsi lu ara wọn bi ejo aijẹ.

Ṣugbọn nigbati ija na pọ pupọ ju, ni Oloye Shittu Bamidele, ẹniti iṣe Aṣiwaju ẹgbẹ Dẹmọ ni Owode, ba sare lọ si Abẹokuta wipe, ki awọn Qga Qlọpa fun on ni Qlọpa lati lọ mu awọn ẹgbẹ UPGA ti awọn jijọ ja.

Ni oga awọn ọlọpa ti o wa ni Tesan ni ọjọ na ba pe awọn ọlọpa mẹfa wipe ẹ tẹle Oloye Shittu Bamidele lọ si Owode ni irọlẹ ọjọ na.

Ṣugbọn awọn ọlọpa mẹfa na yio fi de irọ ni awọn enia kan ti lọ ge igi gẹdu nla kan si oju ọna, nigbati mọto awọn ọlọpa na si de ibi igi yi, nwọn duro nitoripe ko si ọna mọ fun wọfi ti nwọn tun le gba wọ inu ilu.

Nigbati awọn enia na duro nibiti nwọn ti nronu ohunti awọn le se ni awọn enia kan ba yọju si wọn lati inu igbo nitosi ọdọ wọn

Were igbẹ la fẹ ewe, oko ba fẹ ilasa ni awọn ọlọpa na ba bẹlugbẹ ti nwon kosi ran ti lati gbe moto wọn

A gbọ wipe ninu ija ti o ṣẹlẹ larin awọn enia na Oloye Shittu Bandele ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ku bamubamu ni oju kanna nibiti nwon gbe nja

Ninu awọn ọlọpa ti nwọn ran tẹlẹ Oloye Bamidele awọn mefa ni nwọn ko ti gburo wọn mọ ti nwọn ko ri oku ati aye wọn titi di igba ti a fi nkọwe yi ni alẹ ana.

### JẸBẸTẸ

Ṣugbọn nigbati Irohin oh nti o ṣẹlẹ si awọn ọlọpa na ni oju ọna de ọdọ awọn ọga ọlọpa ni Teṣan, jẹbẹtẹ gbe ọmọ le wọn lọwọ, nwọn ko si mọ ohunti nwọn le ṣe mọ.

Were ni ọga awọn ọlọpa Abẹokuta ti ranṣẹ si ọga Agba fun awọn ọlọpa ni Ipinlẹ Iwọ Orun, Oloye Qdọfin Bello, ohun ti nwọn ri ni Abẹokuta, ati bi awọn ti ṣe ranṣẹ si ibiti rogbodiyan na ti ṣẹlẹ.

Lafarabara ni Oloye Qdọfin Bello ti kuro ni Ibadan ti o si wa si Abẹokuta fun rarẹ.

Nigbati o de Abẹokuta ni on ati ọga Agba awọn ọlọpa fun ilu Abẹokuta, Ọgbẹni Gabriel Amu ati oga agba fun awọn ọlọpa Ijọba ibilẹ Abẹokuta Oloye S L Olujobi ba gbe moto ti gbogbo wọn si jijo lọ si Owode lati lofi oju won ri ibiti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ.

Ṣugbon ki awon oga olọpa na to lo si owode awon ti koko ki awon ọlọpa sinu mọto miran wipe, ki nwọn tele awọn lọ si ibiti awọn nlọ ki o maṣe ṣe awọn nikan ni oju ọna ati ni arin ilu na

Ṣugbọn bi awọn Qlọpa ati awọn Qga wọn ti ṣe wahala to na ni ana ati lati ọjọ Ẹti ti o kọja lọ yi to, nwọn ko ti ri oku ati aye awọn Qlọpa mẹfẹfa na.

Nigbati ija ṣẹlẹ larin awọn enia na, a gbọ wipe, nwọn ṣa Oloye Shittu Bamide'e pa patapata, ti o si ku ba mubamu ni oju kanna,

Nibiti awọn enia na gbe nja, nwọn tun ṣe Qga Qlọpa kan, Ọgbẹni Bankọle l'eṣe ninu ija na, nigbati awon Qlọpa yoku de, ninu agbara ẹjẹ ni nwon ti sare gbe e lo si Ile Iwosan Abẹokuta.

Irohin awọn Dokita Ile Iwosan Abẹokuta so wipe, Ọgbẹni Bankọle wa ni apakan Orun ati apakan aiye inu Ile Iwosa- na nisisiyi nwọn ko si le sọ ohunti yio gbẹhin aisan rẹ na.

A gbọ wipe, nigbati awọn enia na ja tan, nwọn tun da ina sun mọto awọn Qlọpa eyiti nwọn ngbe lọ si Owode pelu ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ, Oloye Shittu Bamidele.

### IBERE

Nigbati oniwe Irohin wa ti o wa ni Ilu Owode bere ọrọ lọdọ Oloye Qdọfin Bello ọga agba fun awọn ọlopa Ipinlẹ Iwọ Orun Oloye Odọfin Bello kọ lati dahun Ibere na ko si sọ ohun kankan si ibere na

Ṣugbọn Irohin awọn ọlọpa Abẹokuta fi ye wa ni owuro ana wipe awọn ọlọpa ti mu awon enia mẹsan kan ti nwọn lero wipe wọn le ṣe iranlọwọ fun awon ninu ọrọ ti o de lẹ yi

Ironin na tun se ala

## ALHAJI BALEWA LO SI ILU OYINBO



IKẸJA: Ni deede agogo meji ọsan ana ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ni Irohin kan de si inu Ile iṣẹ wa wipe, Qlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapo Ijọba orilẹ

WO OJU EWE KẸFA

# ẸGBẸ ỌRẸ MẸTA OMUPO KO PE MẸJI (APA KEJI)

Mo ki gbogbo ẹnyin ẹgbẹlẹgbẹ ilu Omupo ati papa julọ awọn ẹgbẹ ọrẹ mẹta ti ilu Omupo ni ilẹ Igbomina eyiti mo ti sọrọ diẹ nipa ẹgbẹ na laipẹ yi, ṣugbọn mo tun tọrọ gafara lọwọ awọn ẹgbẹ na awọn bi Ọgbẹni R A Bakare ti iṣe Akọwe ẹgbẹ na ati Ọgbẹni Amoda Giwa bakanna ati awọn ti emi ko ranti orukọ wọn nipa aṣiṣe diẹ to wa ninu ọrọ mi to jade loṣu to kọja nipa ẹgbẹ na.

Gẹgẹbi mo ti ni ero si pe ẹnyin to nka ọrọ mi nipa ẹgbẹ Ore mẹta ilu Omupo yio jẹ ohunti yio dun mọ mi ninu ti nba le ri awọn enia ti yio kan mi lẹ hin nipa ọrọ ti mo nsọ nipa ẹgbẹ na tabi eyiti yio jẹ aleebu awọn ẹgbẹ na tabi emi ti o kọ ọrọ nipa ẹgbẹ na.

Mo ro pe mo sọrọ diẹ nipa awọn ohunti o jẹ wipe o mu iwuri wa eyiti awọn ẹgbẹ na nṣe eyiti mo fi sọ pe ẹgbẹ na ko pe meji gẹgẹbi akọle ọrọ mi loke iwe yi ati pe mo si ro ero okan mi jinlẹ ati pe mo ri ohun to wa emi lori ti mo fi kan saara si ẹgbẹ na.

Gẹgẹbi owe awọn Baba wa eyiti o lọ bayi pe. Bi ọmọ ẹni ba dara o yẹ ki a sọ ṣugbọn ki iṣe wipe ki a fi ṣe aya toto ẹuyan alagba ati awọn ẹgbẹ Ọre mẹta Owe mi na yio je ti ayin o.

Nigbati mo gbe oye wo gbogbo ohunti awọn ẹgbẹ na nṣe eyiti o jẹ pe emi ko ti ri iru ẹgbẹ to ṣe eyiti o fẹ jọ ni ilu Omupo ati papa ni ilẹ Igbomina ninu awọn ti o wa ni ilu Eko ati pe mo si mọ oriṣiriṣi awọn ẹgbẹ ọmọ ilẹ Igbomina ni ilu Eko loni ṣugbọn ti awọn ti o wa ni ilẹ Igbomina ni emi ko le sọ, ṣugbọn mo lero pe lagbara Oluwa ti o ba di iru asiko yi l'ọdun to mbọ mo ro pe ma si le sọ nipa awọn ẹgbẹ ti o wa ni ilẹ Igbomina ti ki iṣẹ ni ilu Eko.

Mo ro pe gbogbo ẹnyin Onkawe mi lo nba ọrọ mi lọ nipa ọrọ ti mo nsọ lori ilọsiwaju ti no ntọka si eyi ti mo ri pẹlu ẹgbẹ Ọrẹ mẹta ti ilu Omupo eyiti mo sọ pe ko si iru rẹ ninu awọn ẹgbẹlẹgbẹ ni ilẹ Igbomina ati pe ko si ohun ti o jẹ pe ni aleebu ti awọn ẹgbẹ na ṣe.

Awọn ẹgbẹ yi si mọ eto nipa ohun wọn ati awọn enia rẹ le ṣe ti ilọsiwaju eyiti o jẹ wipe lona miran

## LATI ỌWỌ

## 'Bayọ Tiamiyu

eyiti o jẹ wipe o le tun mu ọmọ anfani wa si arin ilu ti o le jẹ pe igbega gbogbo awọn enia ilu na laijẹ wipe fun awọn ẹgbẹ na tabi awọn enia wọn nikan.

Gẹgẹbi ọrọ ti mo ti sọ loṣu ti o kọja nipa pe ki awọn lẹgbẹ lẹgbẹ yoku ni ilẹ Igbomina mura giri ki nwọn tẹpa ẹsẹ rere eyiti iṣe ti awọn ẹgbẹ ọrẹ mẹta ati pe ki olukuluku fi ma ṣe iwa ha

Mo ro pe awọn ẹgbẹ miran to wa ni ilẹ Igbomina ati paapa julọ ni ilu Omupo eyiti o jẹ wipe ti ara wọn nikan ni nwọn ja fun ṣugbọn eleyi ko tẹlẹ ninu ẹgbẹ Ọrẹ mẹta ati pe gbogbo ohun ti wọn ba tẹle lo ni eto eyiti o jẹ wipe pẹlu ọgbọn, oye ati lakaye to pe ni nwọn fi nṣe ọna bi ilọsiwaju yio ti wa fun awọn enia ilu nwọn ati pe ọna bi ilu wọn yio fi jẹ wipe a dabi ilu miran

## Iwa Igberaga

Gẹgẹbi mo ti nsọrọ yi ni awọn ẹgbẹ miran wa to jẹ wipe iwa tẹnbẹlẹkun ẹgan-mani ati Igberaga lo kun inu awọn ẹgbẹ miran ti o jẹ wipe mo ti ri oju ri iru awọn ẹgbẹ bẹ eyiti ko si ba oju mu lati ma gbọ iru nkan bẹ eyiti ko tọ rara

Mo ro pe iru nkan bayi ko ti sẹlẹ lati ọwọ awọn ẹgbẹ ọrẹ mẹta bi nwọn ti ni eto nipa bi ẹgbẹ le se lọ siwaju bakanna ni nwọn ni ẹmi irẹi, ti ko si pe ẹnikan jẹ Onigberaga ninu nwọn

Bi o ba tilẹ jẹ wipe ninu awọn ẹgbẹ na ti jẹ ọmọ ilẹ Igbomina Asiwaju Ijoba ti tabi nisisiyi ko si pe to eto ofin nipa ẹgbẹ to wa lọwọ wọn eyi ko si eyiti o gbọ- dọ ra ọfin ti nwọn ti se sile fun ara wọn

Mo tun gba awọn ẹgbẹ Ọre mẹta ni imọran ati peki nwọn mase sọpe ẹgbẹ ti nwọn ni awọn yio se eto akoso rẹ bikose wipe ki nwọn fun awọn miran ti ko ni ọgbọn nipa ẹgbẹ ṣise ni ilana ati le tẹle ilana eto ẹgbẹ eyiti yio mu ilọsiwaju wa.

### AWỌN IYAWO

Gẹgẹbi mo ti sọrọ nipa eto ti awọn Iyawo ẹgbẹ Ọrẹ mẹta tẹle eyiti o jẹ wipe ko si iru rẹ ati pe mo tun fẹ ki awọn Iyawo ẹgbẹ Ọrẹ mẹta tẹle eto ẹgbẹ awọn ọkọ wọn tabi pe ki awọn da ẹgbẹ tiwọn silẹ eyiti mo gba wọn ni imọran lati ma a pe: Ẹgbẹ ọrẹ mẹta eka Obinrin.

Nipa ọna bayi eleyi yio mu isọwọpọ wa larin awọn iyawo ẹgbẹ Ọrẹ mẹta ati pe ki yio jẹ wipe awọn ọkọ nyin nikan ni o fi gbogbo eto idagbasoke ilẹ ilu Omupo si lọwọ bikoṣe pe, agbajọ ọwọ ni a fi nsọ aya

Bi awọn ẹgbẹ Ọre mẹta ti ba eto ẹgbẹ wọn lọ ba kanna ni nwọn nṣe eto miran eyiti o tun mu eto iṣe Aje wa si ilu Omupo ṣugbọn emi ki yio mu enu ba eleyi loni o di ọjọ miran ti pe emi ko si fe lodi si eto ẹgbẹ Ọre Mẹta e jowo ki e fi ori ji mi nipa eleyi. Ṣugbọn ti nba gba aṣe lati mu enu ba eleyi ma si fi awọn ohun ilosiwajd eyiti o to fun omo enia lati ṣe han ẹnyin Onkawe mi O digba die.


## EGBOGI JEDIJEDI

BERE FUN EGBOGI

### "CYCLEVEN"

Arun Jẹdijẹdi jẹ okan ninu amodi ti o buru ni patak fun Ọkunrin ti o si lagbara lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri odẹ nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la le ri mẹwa ninu ogọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara. Awọn ẹlomiran lere wipeboya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyo jade lati omusu ku ni, pa bẹ awon o bo lowo rẹ palapata

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara: Lẹnin odun uie iyonu rẹ o siton ma bẹrẹ bakanna, Orisirisi Jẹdijedi ni o wa ini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbonse dede tabi lojo-jumo, elomiran nipa ijoko ul ojukanna selu lojojumọ tabi gigun keke ylogere (Basikulu) pupo elomiran ewe nipa jije Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupo ju. Jedije-di oriṣiriṣi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o ba nyo jade ninu o lusu tabi ti o ba nmu wa lẹhin igbonsẹ tabi ba uyo ti o ba ṣe igbotsẹ tan ni, tabi ti nrun o ninu musu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon Oyinbo Jamani fere wa id rẹ ko ki o si dawo o iṣi me-to mo da u wipe iwo yio ro lowo Je i p tapata alafia yio de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogi sa igboro ilu Nsira Bere re ni:—

Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Streer Lagos
ATI NI ṢỌBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

## Iwe si Olotu Irohin Imole

### A Tun Nfẹ Itan Miran

Idunnu mi ni yio je bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye lati dupe lọwọ Ọgbeni Shoyinka onitan ajiran itu awọn osu fun awọn itan aladun ti o maa nsọ ninu iwe Irohin Imọlẹ nigba gbogbo ti o maa ti nda wa lara ya eyiti okun fun ọgbọn, imọ, ẹkọ, laakaye, oye o ti ọgbọn ajinle



Ọgbeni J. O. Shoyinka

itan ti Ọgbeni Shoyinka nsọ lọ lowo yi eyiti a nka lo ko ti sọ tan rara ṣugbọn a ko mọ ohunti o se ti a ko tun fi gbọ itan na mọ ninu iwe Irohin Imọlẹ tabi Ọgbeni Shoyinka kọ itan na ranṣẹ si Olotu, Olotu ni ko tẹ itan na jade fun wa ni?

Inu wa yio dun lọpọlọpọ bi ọgbẹni Shoyinka bale pari itan na eyiti o ti nsọ lọ ni nitan bi osu meji sẹhin

Bi o ba si ṣe wipe Ogbẹni Shoyinka ba sọ itan na ni ẹjọwọ atun nfẹ itan miran lati ọdọ nyin laipẹ bi oba tilẹ le baamu a nfẹ itan na ki ọdun yi to pari tabi ti o ba ti di ibẹrẹ ọdun ti mbọ yi ki o le jẹ wi pe itan tuntun ni e o fi bẹrẹ ọdun tuntun ki o wa jẹ wipe ọdun tuntun itan tuntun

Olotu mo du ẹ aye ti e gba mi ninu iwe Irohin nyin ki Olọrun jẹ ki ọdun tuntun na de ba gbogbo wa layọ ati Alafia

Emi ni
Owọade Alabi
COTONU

zo kun fun ọgbọn ati oye lati kesi oga agba awọn Ọlọpa ti apapọ ile Naijiria Ogbeni L. O. Edet nipa iwa ti awọn Ọlọpa ti nwọn ko wa si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati Ipinle Ariwa ile Naijiria eyiti o fẹ wipe ki iṣe isẹ rere ni awọn Ọlọpa na wa ṣe ni Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria.

Eleyi ti fi han gbangba pe ise awọn ja duku omo ẹgbẹ Oṣelu ni awon Ọlọpa to wa si Ipinlẹ Iwọ Orun lati Ipinlẹ Ariwa ngba ṣe ni Ipinlẹ na ati pe nwọn ko ṣe iṣe ti o tọ lori eto ofin ile Naijiria eyi i oyẹ ki awọn ọlọpa na ṣe ati pe awọn ẹgbẹ oṣelu ni nwọn wa ja fun.

Eleyi yio tun je ohunti o tọ ti o si ye bi Oga agba awọn Ọlọpa fun orilẹ ede Naijiria ba le ṣe iwa di si akoriyan awọn Ọlọpa ti nwon ko lati Ipinle Ariwa tabi pe ki nwọn tete da wọn pada nitori pe ko si ohun rere kan ti awọn ọlọpa na wa ṣe bikoṣe pe ki nwọn tun da nkan miran sile.

Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi ọkọ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o.

Emi ni
Ọmọ Odua
IBADAN.

### Mo Kan Saara Si Ogbeni Dawodu

Olotu, Jọwọ gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati ki Alaga Ile Igbimọ ti Ijọba Ibilẹ Ilu Eko Ọgbẹni Ganiyu Ọlawale Daodu nipa iṣe ti o koko ṣe nigbati o de ori aga gẹgẹbi Alaga Ijoba Ibilẹ Ilu Eko nipa to nko Malu na oju ọna Apapa eyiti Ijoba ti o ise Alaga rẹ tete ṣe eto lati fi moto ma ko awọn Malu na lo sibi ti nwọn yio ti ma pa awon malu na.

Eleyi jẹ ohunti o wu awa to ngbe Apapa lati ri iṣẹ nla ti Ijoba Ibilẹ Eko koko ṣe lati jẹki a ri ona rin ti awọn malu da silẹ to ba di nkan bi agogo mẹfa irọlẹ ati pe ọpọlọpọ iṣẹlẹ nla lo ma nṣẹlẹ nipa ki awọn motọ ma kolu ara wọn nitori awọn to nda malu kọja ọna na ti nwọn ko si bikita

Imọran mi si Ijọba Ibilẹ Eko ni pe ki nwọn jẹki awọn moto yi pọju gẹgẹbi o ti wa lati le ti ma ko awọn malu na lọ ona papa

Inu awa enia ti ngbe Apapa ati Surulere si dun fun iṣẹ ribiribi ti Ọgbẹni Dawodu ṣe nigbati o gba eto akoso Alaga Ijoba Ibilẹ na.

Emi ni
Tejudeen Adesanya
EKO

### Edet O di Owo Nyin

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye die ninu iwe nyin


## WANTED

Advance Apprentice and Apprentice Printers.

Apply In Person

Irohin Imọlẹ's Office
16, Bamgbose Street,
LAGOS



# Kere o Kere o! Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanun Egbogi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pelu meji re ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na njẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o ti wu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun nigba kugba ara wiwo, Ẹsanri ẹhin didun sisan ati aika riran kedere ko di ro buruku ara, aisan Onigba meji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki ẹja ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ se enia nipa sisọ di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ORỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile mẹfa abọ (6/-6 pere Igo kekere ṣile mẹta abọ (3/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba
LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.



### Angelina Super -- Rose
(O TI LỌ WA JU)

Eleyi ṣẹṣẹ jade ni ko si nita rara ṣẹṣẹ jade akan a ko mo ibiti o lọ ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju"

Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lọmọde lagba ọkunrin ati lobinrin o tun wa fun iran didi ati kiko elolu o nmu ika ọkunrin pap ma dan ti o si jọlo o ma nu ara ni ẹwa ak tun awọ ara yio jẹ yọ jade perepere fun enia dudu ba loo yio ma dan gẹgẹbi jigi enia pupa aga ṣe lyen ti wa tẹlẹ.

Tere sare wa tabi ki o kọwe fun tirẹ loni ki o to tan nt nternational Cosmetic Industries" 36' Ọmọwunmi Street, lehin kanCu Mushin Ẹ toju ara ati iran nyin ẹ ne pelu awujesulọ nyin owo pọku ni 1/3d fun ẹyọ kan 15/- fun mejila ọni fun alaje si.

# ITUMỌ ALA

Nwọnyi ni awọn ibere ti a ri gba. Awon itumọ wọn ni yi Eyi si ni lati kilọ fun awọn onibere pe ki nwọn ma kọwe wọn daradara, ki a ba le ma ri i ka, enikẹni ti ko ba ṣọ tire rekete ko ni ri itumọ ala rẹ ka ninu Iwe.

Babatola Ilufẹmi Badagry — Ṣọra nipa irin ajo oju omi toripe iku ojiji mbẹ fun o

Amos Ojo Akure — Maṣe ba enia ja ni asiko yi, enu ọmọ enia ma ba ti ọwọ re bọ

Bisiriyu Abẹokuta — Iwọ yio gbọ iro rere lati ọna jinjin re e, ti yio ṣe ọ ni anfani.

Samuel Sheteolu Ilaro — Okiki rẹ yio kan iaseko yi ṣugbọn ṣọra lodọ awọn ọrẹ, ki nwọn ma ba a da si ọ lọrun

Aduke Faramobi Lagos — Oke iṣoro rẹ yio di pẹtẹlẹ fun ọ. Ṣọra lọdọ orogun rẹ

Taibatu Isalẹ Eko Lagos — Ire ajẹmọnu kan de fun ọ tan uisisiyi, Ṣọra lati ma a fiọu han awọn ti o npe ni ọrẹ.

Akiyesi:- Fi ala t rẹ ranṣẹ ngo si tumọ re fun ọ lọfẹ
Josefu Ala
P O Box 159
Mushin

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUAIRUS (Jan 22 Feb 20) Faaji ati ifọkanbalẹ rẹ lo i yio ga jojọ awọn ti o mba ọ lopọ yio ni ifọkanbalẹ si ọ gbogbo oro iṣoro kekeke ti o wa nibẹ yio yara pari

PISCES (Feb 21 Mar 20) Bi o ba le tun ara ṣe iwọ yio gbadun gidigidi gbogbo wahala ati awọn ohunti o ndanu rẹ yio yara kuro wa akoko Iti lọ ri awọn ọrẹ rẹ

ARIES Mar 21 April 20) Maṣe jẹki earẹ mu ọ ki o si jẹki oti rẹ pa gbogbo ohunti o ni lati ni akoko yi ki o sọ ọ diẹba miran Patẹki rẹ ni wipe ki o toju emi ara rẹ

TAURUS (April 21 May 20) Igbakan mbọ ti o jẹ wipe gbogbo ero to ngba patapata ni yio ṣe ti iwọ yio si bori awọn ohunti o je ṣoro fun lọdọ awọn enia

GEMINI (May 21-June 21) Ara rẹ le gangan tobẹ ti o fi le kapa awọn iṣoro ti o wa fun ọ ṣugbọn ki o kọ ri pe adehun duro ko si s titanjẹ nibẹ

CANCER (June 22 July 22) O yẹ ki o ta ara rẹ ṣe, bi bẹkọ nkan yio bajẹ pupọ nṣe ui ki o ni suru, nitoripe awọn ẹgbẹ rẹ ko gbọdọ gbọ ọrọ aidara lẹnu rẹ, kuku fi ẹnu rẹ mọ ẹnu

LEO (July 23 Aug 22) Egbogi ti o ba lo loni ire ni jẹ iwọ yio si pọlọpọ ere jẹ pọnkipọnki ni ara rẹ ri iwọ yio ti irohin atata ka i gbọ ti yio si tẹ ọ lọrun

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Iwọ pẹlu yio ri wipe aipe ndara fun ọ ko si tọ ki ma ṣe tabi kan mọ ipade kan ti iwọ yio ba wọn ṣe yio dun yio si ariyarin bi iwọ ko ba gbe ti arino daju

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Enu le ma ya ọ si gbogbo bi nkan ti nlọ si fun lakoko yi mape kominu si tunbọ ṣe suru ohun ti o nfẹ yio tẹ ọ lọwọ di indan Edekoyede ti o si nṣẹlẹ labẹ ile rẹ ko to ohun ti o le mu o ko kominu laipẹ gbogbo rẹ yio s to lo

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) N ṣe ti aiye rẹ yio ma gbadu si aju tẹrin terin ati oyaya ki o si fi ariri ara rẹ pamo ni ile oni

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Bi o ba ngbero lati ṣe ohun titun kan akoko yi gan to ye ki o ṣe, ire wa fun ọ lonakona, ṣugbọn e ni iwọ papai nse lo nmi bi ago o sinesire ọ si sa die nisisiyi

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Ọkan rẹ ko bale nipa ohun k n ti o ngbero lati se, ki o ma si yi lẹ o yi o lenu bi amodi aburadi kan ni de [illegible] o ṣe suru

## APIAS RHUMATIC & DOGES

OJẹ ojulowo kanunhanun egbogi Jamani to lagbara gid fun Iwosan LAKUREGBE to mba enia ja



Orişirişi lakureghe ni o wa lakuregbe Arungan ti o ma nsan enia ninu egungun ara lakuregbe ti o ma nwu enia ni ẹsẹ roboto ti o njẹki ẹsẹ wuwo lati ma rin Lakuregbe ti o ngbe rikerike dinwọ kori bi o ti roran lati lo tabi ki o ma ṣe ayipada ẹsẹ, ara tira bi eyiti enia fi ara obẹ pa ibadi abi egugu ara wiwo, ako iba ahi p pon tabi rirun.

Bi enia ko ba ebajum lati t ju rẹ lasiko o le sa owo pa enia

NIGERIAN MEDICINE STORES
4. Tinubu Square Lagos
Phone 282878 Nigeria, (Ọja Ita Faji
LAGOS

## Iwo Ha Nfẹ Ile Eko Bi?

| | | |
|---|---|---|
| Room | | £3 |
| Room | | £4 |
| Room | | £5 |
| Room / | Parlour | £6 |
| Room / | Shop | £15 |
| Flat | (Lgos) | £20 |
| Flat | (EB) | £25 |

Ti o ba nfẹ okan ninu awọn ile wọnyi yara tete lo ni Ọgbeni ODUS:— 187 Bamgboṣe Street Lagos ni dede agogo merin irolẹ si agogo mẹfa irolẹ. ijafara lewu anfani ala ka i ni eyi jẹ fun ọ pe o ri ile l'Eko

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYNAMIREN** TỌNIKI



ALE-BI-ALE Egbogi Tọ irki amonu tilun ti gbogbo aga ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ d ju fun Akr jebara ati Ajẹbidan iṣẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, n gbakugba fun wahala tab iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan lasan tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ṣefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyia ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi ube lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati s ara di tu pafapata inu rẹ a jilọ ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi yabo dada kAra rẹ yio gbe kankan ni gunba yio sao pẹlu ioq adeubrode iyẹn di j ba

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone.- 22878 Nigeria, (Ọja Ita Fajiẹ

# Itan Awon Asoju Ijọba Ibilẹ Eko

Sikiru Karimu Jenmi je okan ninu awon omo Ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko eyiti awon eniyan yan ni oju Abameta ti o koja ojo ketala osu to koja yi gege bi okan ninu omo Ile Igbimo Aşofin Ijoba ibile ilu Eko



## Ogbẹni S. A Jẹnmi

A bi Ogbẹni Sikiru Arẹmu Jẹnmi ni ilu Eko atipe eni odun mẹtalelogbọn ni işe, Ogbẹni Jẹnmi si je okan ninu ọmo Olọgbe Aili Balogun okan ninu awon ogbokangi musulumi ni ilu Lu Eko

Ogbeni Sikiru Arẹmu ti o ngbe ni nomba 38 Bamgbose Street Eko ni awon enia agbegbe Ward H 5 si yan gegeb Asoju Won ninu ile Igbimo ti Ijọba ibile ilu Eko ninu ibo ti nwon di ni ojo ketala ose kokan odun yi

Ninu ibo na ni Ogbẹni Jẹnmi ti ni ibo ẹdẹgbẹrun o le mẹdogun ibo (9.5 Votes) Ogbẹni Sikiru Jẹnmi si jẹ ẹnikan ti o je gbajumọ enia enitl gbogbo enia mọ adape rẹ ni "SKJ"

Ogbẹni Sikiru Arẹmu Jẹnmi bẹrẹ eto ẹkọ rẹ ninu ile ẹkọ ti Christ Cathedral School Eko, lẹhin ti o jade ninu ile ẹkọ Cathedral School ni o tun lọ si ile ẹkọ giga ti Eko Boys High School lasiko ti Ologbe Robert si wa gẹgẹbi ọga agba ile ẹkọ na

Nigbati ogbẹni Jẹnmi kuro ni ile ẹkọ giga ni o lọ şişẹ ni ile işẹ ti ọkọ oju irin. Lẹhin eyi ni o fi ile işẹ na silẹ ni odun 1960

Nigbati ogbẹni Jẹnmi fi ile işẹ ti ọkọ oju irin silẹ ni o si lọ dẹduro fun ara rẹ ti o si nşişẹ fun ara rẹ titi di isisiyi. Ogbẹni Sikiru Aremu Jẹnmi si jẹ ọkan ninu ọmọ ologbe A K Jẹnmi ti o ngbe ni adugbo Taiwo Street Eko eyiti o jalaisi ninu odun 1955

Bakanna ni ogbẹni Jẹnmi si tun jẹ ọmọ ologbe Iyaana Jaratu Jẹnmi ti işe ọmọ ologbe Alli Balogun ti o jẹ ọkan pataki ninu awọn musulumi ni ọlọrọ lasiko aye re

Ogbẹni Sikiru Jẹnmi si ni iyawo pẹlu ọmọ mẹrin ọkunrin meji ati obinrin meji

Awa Oniwe Irohin Imọlẹ gbadura pe ki ẹmi ogbẹni Jẹnmi gun ki o si le lo ọpọlọpọ ọdun laiye pẹlu idunnu ati alafia

# Ila Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A n O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupo ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu yara pa ayan ati idun

Tete lo ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi o ti şe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu fun ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni şọbu ileitaja kakiri Orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS

AMOS GBENLE & BROTHERS

34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

BERE FUN OJULOWO ADI ELEGBO

# "Congreve's Iodo Form--Ointment'



Ajamatase ni egbogi" ADI-ELEGBO" yi i fun itọju gbo gbo orişirişi "EGBO—ESẸ" ni kakia bi o ti wun ki jọ rẹ ti le pẹ to. Adielegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọti ni bi ẹrẹgẹrẹ ogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara. Lẹhinna oju egbo ti o baji si u yio jeki oju re ru wa soke, yio si pọn daradara fun bakiru ko si mọ werewere ni yio si san patapata. Alafia de si ọ niyen :—

Ri daju gbangba wipe awon şobu ti a da oruko won si isale iwe yi ni ogun ranşe lọ ra. Bibẹko awon Eleru tabi onijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maşe gba rara o.

Bere egbogi yi ni şobu awon :—

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street. Phone 22787

IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,584 MONDAY DECEMBdR 13, 1965 (2D)

## Ijoba Dutch Șe Ileri Lati Tun Omi Wa Șe

EKO-: Minista fun eto Igbokegb ede ti irinna Alhaji Zanna Bukar Dipcharima so ni ojo ojo Bo tise ojo kejo osu yi pe ile Holland tise ileri fun on pe awon yio ran ile Naijiria lowo lati tun awon omi wa ti oko oju omi nrin se fun wa nitoripe opolopo ninu awon oju omi na ni o nfe atunșe ati wipe aw n oko oju omi ki ri aye nibomiran.

Minista yi nsoro na fun awon oniwe irohin ni kete ti o ti irin ajo re si ilu okere de eyiti o fi ese kan de awon ilu bi Holland Western Germany ati Spain.

Alhaji Dipcharima tun so pe asoju ile Dutch ti o wa ni Naijiria ti bere si maa wa ona ti omi ti oko ngba ni Eko ati Port Harco urt se paapa kainji ti nwon nse lowo bayi ti o wa larin odo Oya (Niger) ati Benue je eyiti awon ojogbon se nse lowo bayi Minista na ni ibiti awon ilu Dutch ti nse oko oju omi je eyiti o ba ode oni mu pupo.

Minista na so pe: ile Dutch yio ran Naijiria Novo ati Calaba lowo lori ise awon ti ntun oju omi ti oko ngba se o ni gegebi eto idagbasoke ile Naijiria a ko gbodo mu ise oko oju omi dinku nibe

Alhaji Dipcharima wa pari oro pe gegebi irin ojo re s'ile Germany ile ise oko oju omi na awon oko oju omi ala lati ile Germany eyiti yio lagbara lati maa ko awon oja ile wa bi Ekuro Epo pupa' koko owu, epa ati igi Gedu lo si awon orile ede agbaiye rira awon oko ala yi yio jeki airi ise se dinku atipe yio jeki irin ajo oju omi gboro si.

# AWON ENIA MARUNDIN-LOGOJI TUN JARE ĘJỌ

Akurę:- Idunnu șubulu yọ ni ọjọ Ọjọ 'Bu tișe ọjọ kẹsan oșu yi ni ilu Akurę nigbati adajọ agba ti ile ejọ Ijọba to wa ni Akurę Iyaafin Adunola Ogantoye ni marunlologbon ninu mejidinlogoji ti Ijọba nba șe ejọ apania ko ni ejo kankan lati ro mo ki gbogbo won ki o ma a lo ni alafia ati idunnu.

Onirohin wa ti o wa ni ilu Akurę so fun wa pe, ile ejo na kun ti kofi gba enia mo, o tun ni bakanna ni ita ile ejo na tun kun fun awon ore, ibatan, ojulumo ati awon abanidaro ti nwon fe gbo bi ejo na yio ti pari si.

Bi nwon ti fe bere ejo na ni awon agbejoro fun Ijoba ba ni awon ko ni ba awon enia marunlelogbon se ejo mo, nitorina awon jawo ni nu ejo ipania ti Ijoba nba won șe.

Gbara ti agbejoro Ijoba ti jawo ninu ejo na ni adajo agba Iyaafin Ogantoye ba ni i nwon ki o ma a lo ni alafia ati fokanbale, bi awon na ti jade ninu ile ejo na ni awon enia ba gbe won soke ti nwon si pariwo Awo! Awo!! titi Olopa kan fi jade lati ile ejo na pe e dake e tile mo pa ariwo mo, a bi e mo pe ariwo yin ndi ile ejo lowo?

Siwaju eyi ni igbakeji oga agba awon Olopa Otelemuye Ogbeni Azuquo lati ile ise awon Olopa Otelemu ye to wa ni Eko so fun ada jo pe agbejo Ijoba ni awon ko ba awon Odaran se ejo apania mo a fi awon meta ti o ku awon meteta na ni Michael Agbatiogun. Daniel Awotiku ati Edward Awotiku.

Ęjọ ti nwọn nba awọn na șe ni pe nwọn pa Olori egbe Demo kan ti orukọ rẹ nję Anthony Shangotoke, ni ọjọ kini osu kokanla odun yi ni ilu kan ti o nje Igbara Odo.

Nigbati ọwọ Ọlọpa kọ tẹ awọn ọdaran na, nwọn ko ti ieki nwọn rojo niwaju adajọ nwọn si da wọn duro si ọgba ewọn titi di ọjọ ti adajọ fi marunlelogbọn silẹ ninu wọn, ti nwon fi tun fi awọn mẹta ti o ku si ọgba ẹwọn titi yio fi di ogunjọ oșu kejila odun yi, ile ejọ ko si gba iduro awọn mẹtẹta ni nwon ba gbe wọn pa da si ọgba ewọn.

Ninu ile ejọ kanna ni ijọba tun nba awọn meji șe ejọ apania orukọ nwon ni Cosmos Oshodi ati James Owolabi nwọn ni nwọnpa Ọkunrin kan ti orukọ rẹ nję Anthony Famuyide ni ọjọ kini osu kọkanla ninu ọdun yi ni ilu Igbara Odo

Nwon ko ti gbo oro lenu won niwaju adajo ni adajo agba na ba sun gbigbo ejọ si ogunjọ osu yi gege bi ti akọkọ

Niwaju adajọ agba kanna ni nwon tun ko awon marun wa pe nwon pa ọkunrin ti oruko re nję Joshua Oni ni ojo kini osu kokan la ninu odun yi

Awon Ọkunrin na ni John Owoeye Omidare Ękundayo Fadu ru Adumadeyin Araolu ati Simeon Opeloyeru esun ti nwon ka si won lese nipe nwon pa Joshua Oni ni ilu Igbara Odo

Nwon ko ti so ti enu won fun adajo ni adajo ba sun gbigbo ejo na si ogunjo osu yi

Gbogbo won si wa ni itimole awon olopa bayi.

## Lati Oju Ewe Kini

O ni iwa ti nwọn nhu na nfe ero t'ope, o ni kakaki nwọn ki o maa mojuto alafia awọn enia șugbọn pipa ni awọn Ọlọpa Hausa npa awọn enia ti nlọ wọrọ.

Ni ipari ọrọ Ọgbẹni Aluko ni o ti kesi Alhaji Balewa pe, ki o pe awọn ti ori nwọn pe ati awọn ọ ọgbọn ilẹ Naijiria jọ ki nwọn wa ọna ti edeaiyede to wa ni Ipinlẹ na yio fi dopin ni kiakia.

LATI OJU EWE KINI

edo Naijiria yio ba ọkọ ofurufu kuro ni Ekoni owu rọ yi ọjọ Aju ti ișe ọjọ kẹtẹla oșu yi lọsi ilu Ọba Oyinbo.

Irohin na tun șe alaye siwaju wipe, nitori rogbodiyan ati ote ti o wa ni Ori lẹ ede ilẹ Rhodesia nisisiyi ni Alhaji Balewa nlo si ilu Ọba Oyinbo fun.

Oniwe Irohin wa Ejongboro yio lo si ibudo oko Ofurufu ni Ikeja ni on lati lo ri Alhaji Balewa ati lati tun bere awon oro kan lowo re nipa irinajo ti o nșe lo si ilu Oyinbo na loni.

LATI OJU EWE KINI

awon enia mefa to ku si je Okunrin

Titi di igbati afi nkọ iwe yi ni alẹ ana awon olopa na ko tiri oku ati aye awon ọlọpa mẹ fẹfa ti nwọn nwa na.

Bi aba ti tun gburo ọrọ na si ao tun ma a sọ fun nyin o.


## ALEBIOSU BOOKSHOP

13, BAMGBOSE STREET, PHONE (2 1 3 0 4) LAGOS

LADIES & GENTLEMEN/

As your problem is ours, therefore we have got in Stock, Seasonal Lovely & interesting Xmas Cheque and Xmas Cards in assorted types as:-

| | | | |
|---|---|---|---|
| 1 | To my Darling | 2 | To my Sweet Heart |
| 3 | ,, my Lover | 4 | ,, One I Love most |
| 5 | ,, my Boy Friend | 6 | ,, Husband |
| 7 | ,, my Wife | 8 | ,, my Sister |
| 9 | ,, Brother | 10 | ,, my Friend |

You will be mostly impressed if you come to the above named Bookshop for your Seasonal Greeting Cheques & Xmas Cards,

WISHING YOU HAPPY CHRISTMAS IN ADVANCE


Printed & Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 45 Campbell Street Lagos. 13/12/65